# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 831 LAGOS SATURDAY AUGUST 4, — AUGUST 10 1962. KỌBỌMEJI (2D)


### OBA GBA IDA TAN:

# Owo Ori Fe Da Ija Sile Ni Ilorin

ILỌRIN— Ọrọ owo ori sisan fẹ b'Ige bi Adubi ni ilu Ilọrin nitorina awọn ẹgbẹ ọdọ NPC ti ṣe wosika pataki ranṣẹ si Mallam Sanni Ọkin, ọmọ Ilọrin tiṣe Minisita Alamojuto nkan ọgbin ni Kaduna, wipe ki o jọwọ ki o gba awọn nipa ọrọ na. Nwọn ni ponun mẹta o-din ṣile meji abọ owo talaka ti nwọn ni ki awọn ma san lọdun yi ti pọ ju; iṣẹ koi ti si nilu. Ile iṣẹ iṣanọ ti nwọn ṣeṣẹ nkọ koi ti pari ti nwọn yio fi gba enia sibẹ. Awọn ọdọmọde NPC na ni wahala owo ori na pọ ki Ijọba Ipinlẹ Ariwa ba awọn fi oju agba yẹ ẹ wo.

Onirohin Eleti Ọfẹ ni rogbodiyan ti o tun wa ni Ilọrin nisisiyi ni ti awọn ogunlọgọ onişẹ kapinta ti nwọn nṣe iṣẹ labẹ Ijọba Ibilẹ Ilọrin ti awọn Ijọba na da duro lẹnu iṣẹ. A gbọ wipe awọn Ijọba Ibilẹ na ti fi akee kọri wipe ko si owo 'rẹmilẹkun' fun awọn ti nwọn da duro na, ọpọlọpọ wọn ni nwọn si ti ha ni iwe owo ori gọbọyi.

Awọn iyawo awọn kapinta ti [illegible] wọn ti n n ira lati lọ si si oke Ajẹlẹ lati sunkun ba Ajẹlẹ tuntun ti o ṣẹṣẹ de wipe ki o gba awọn lọwọ ebi ọgiji fọwọ mẹ'kẹ.


WO OJU EWE KẸTA (3) FUN IROHIN Ọba Ilọrin pẹlu IDA aṣẹ ti Sarudana Sokoto fun un ni Kaduna.



## THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS,

LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell

Telephone London Wall 4303
Cable & Telegrams Nathaniger; London
Head Office Representative in London.
E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG



Advt. No. 109

# IKEDE

OWO ATIJỌ TI WEST AFRICAN CURRENCY BOARD

Lati ọjọ kini oṣu July, 1962, eyiti iṣọ oṣu keje ọdun yi, gbogbo owo atijọ patapata ni pepa kọrẹnsi ati ṣile pẹlu owo wẹwẹ miran bẹ ti West African Currency Board ti kuro labẹ ofin ni jake jado ilẹ Nigeria. Owo yi ko ni ṣe na mọ fun sisan gbese tabi ki o wulo fun tita tabi rira ọja ni ṣọpu ati ni ọja. Ṣugbọn owo wọnyi ṣi ni iye lori ati wipe ẹnyin si le ṣe paṣi-parọ wọn ni gbogbo Bank.

Lati ran yin lọwọ, Central Bank ti Nigeria ti ṣe eto pẹlu gbogbo Bank pe ki wọn ma ṣe dẹkun lati ma ṣe paṣi-paro owo pepa kọrẹnsi ti atijọ l'ọfẹ fun awọn enia titi di ipari oṣu September, 1962, ti nṣe oṣu kesan ọdun yi ati fun owo ṣile ati awọn isọngbe rẹ titi di pari oṣu December, ti nṣe ipari ọdun yi.

Nitorina a bẹ gbogbo yin patapata lati mu owo atijọ ti o mbẹ lọwọ yin lọ si Bank ti o ba sun mọ yin ki Ẹ lo ṣe paṣi-paro won l'ofẹ si owo Nigeria titun ti Central Bank fi si ode ni iwọn ọdun mẹta sẹhin. Ẹ ma ṣe jaf'ara.

Gbogbo ẹniti ko ba parọ owo atijọ ọwọ rẹ si owo Nigeria titun titi asiko ti a fi silẹ fun yin ba fi pari yio san owo fun Bank nigbati o ba fẹ ṣe paṣiparọ owo atijọ rẹ lẹhin ọjọ wọn yi.

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
LAGOS.

**W. A. TIBBLES**
GENERAL MANAGER

# Awo rawo

## Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22–Feb 20) Ki o gba iyanju ki o bọ okun ajara kuro lọrun rẹ nitoripe nkan ti o wa ni iwaju rẹ pọ, awọn ẹnikan si nwo ẹ boya wa le gbe de ori.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Ṣọra pelu onjẹ a jẹ ju ki o mọ si ṣe hu'-wa ifaa ni, ẹ jẹ ki njẹ daradara. Iwọ paapa mọ wipe ko si agbara tabi okun ninu rẹ.

ARIES (Mar 21–April 20) Nkan ti ọkan rẹ ba ro ni ki o tete ṣe ki o mọ si ṣe ba ara jẹ. Tẹju mọ iṣẹ ọwọ rẹ lọsẹ yi.

TAURUS (April 21–May 20) Nkan kan a ṣẹlẹ si ọ ninu ọsẹ yi ti a jẹ ki inu rẹ dun pupọ ju, sugbọn ki o mọ ṣe ṣe ni ayọ ti akere yọ ti o fi fi apa ṣẹ.

GEMINI (May 21–June 21) Gbọ imọran ti awọn ti o fẹran rẹ ba fun ọ; maṣe ṣe iṣe "emi ni mo gbọn ọgbọn pupọ ju.

CANCER (Jun 22–July 23) Ṣọra pupọ ki o ṣe ẹrọ rẹ ni atẹwọ lara ki o mọ ba enia kan ja, ife ni ko mọ fi ba awọn enia ti o ba mba pade ninu ọsẹ yi lọ.

LEO (July 24–Aug 22) Oju ni alakan fi nṣọri-tejumọ iṣẹ rẹ ki o si fiye sọra pupọ nipa arun ki a eun ki ọ mọ tete da.

VIRGO (Aug 23–Sept 23) Maṣe ba ara je rara, wa ri ojulumọ kan ti yio fi ifẹ han siọ ti yio ran ẹ lọwọ.

LIBRA (Sep 24 -Oct 23) Ki o to ṣe nkankan ninu ọsẹ yi ki o gbe yẹwo daradara. Ki o si ṣọra pẹlu ọrọ enu rẹ ati lọdọ obinrin.

SCORPIO (Oct 24–Nov 22) Awọn ọrẹ tabi ẹbi le k'ẹgan rẹ, ma di wọn lohun; maṣe ọrọ rẹ ni f'ara lọpẹ f'ara lokuta.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Gbọngbọn ko si, a fi ẹniti o nti ara rẹ. Rere ni ki o lo agbara ti o ba ni lori enia si ninu irin ajo ti ọsẹ yi.

CAPRISCORN (Dec 23– Jan 21) Ọgbọn ọlọgbọn ni ki o fi ṣe ọgbọn ninu ọsẹ yi. Bi o ko ba ṣe bẹ iyoku di ọwọ rẹ.

## Joseph Folayan Lo Si Ilu Oyinbo

Ni ijẹta ọjọ Alamisi ni ọdọmọdekunrin kan ti nwọn npe ni Joseph Ibukunle Fọlayan, ọmọ Iludun ni agbegbe Ilọrin, wọ ọkọ-ofurufu ni Ikẹja ti o lọ si ilu Oyinbo fun ijinlẹ ẹkọ ti o tun fẹ ko ni Amẹrika.

Ibikunle jẹ ọmọ Ọgbẹni Davidi Fọlayan, o si ko ẹkọ ni ilewe ti nwọn npe ni Titcombe College ni Ẹgbẹ leti Ilọrin ati ni Science Emergency School, Onikan l'Eko.

A ki awọn ẹbi rẹ, awọn bi Ọgbẹni J. I. Fọlayan (ọmọ Enle), J. Ọlawoye, Zakiu Ọlawoye, F. Ọlawale ati Baba Sunday pe nwọn ku ilede. Ọlọrun ki o sọ ọ wa ba wa.

Plushes, Velvet, Velveteens, Damask

& Building Materials

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

( 63, Massy Street, Faji Market )

LAGOS. NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

## Lebira Kan Ku Sinu Ọmi Osa ni Apapa

Ni Apapa ni ijẹta, ni a gbọ wipe ọkunrin lebira kan ti orukọ rẹ njẹ Gabriel Robert ti o nṣe iṣẹ lọgba Biney nibiti nwọn gbe nko ẹru sinu ọkọ oju omi ti o nlọ si ilu Oyinbo, ẹsẹ rẹ yọ lori simẹnti, o si bọ sinu omi Ọsa, odo na si gbe e lọ.

Awọn alabaṣiṣẹ lebira na ti o wa ni ebute nigbati jamba na ṣe Ọgbẹni na ni awọn ṣe bi o nwẹ ni nigbati awọn ri ninu omi, awọn ko tete mọ wipe o npọka iku ni, a fi igbati o mu okun ti ko jade soke mọ.

Ọga ibiṣẹ Biney na ti o njẹ Ọgbẹni Borgwu ti lọ sọ fun awọn ọlọpa nipa iku lebira na, nwọn si nwa oku rẹ boya o le lefo ki nwọn ri i gbe.

# Oba Da a Lola



Aworan yi ni ti Ọga awọn ṣọja kan ti nwọn npe ni Brigadier Johnson Aguiyi-Ironsi nibiti o gbe nfi mẹdali ti ọba ilu Oyinbo, Elizabeth keji fi da a lọla han awọn ọmọ rẹ meji, Thomas ati Caroline, lẹhin igbati o gba mẹdali na tan ni agbala Ọba na ni London. Ọmọ Nigeria ni ọga ṣọja yi nṣe.

**RIKISI PIN**

# Sardauna Fun Oba Ilorin Ni Ida Otito

KADUNA—Laipẹ yi ni Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto tiṣe olori Ijọba Ipinlẹ Ariwa ranṣẹ si Ọba Ilọrin, Mallam Sulu Gambari, wipe ki o fi oju kan on ninu ile ti Ijọba Ipinlẹ na kọ fun on ni Nasarawa ni Kaduna ti nwọn npe ni Premier's Lodge, on fẹ baa sọrọ. Asamasama, o jẹ nṣe ni Ọlọla Ahmadu Bello fẹ da Ọba Ilọrin yi lọla pẹlu ida-onidẹ kan.

Gbara ti Ọba yi, Malam Sulu Gambari pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ ti de ibẹ ni Ọlọla Alhaji Amọdu Bello na ti bẹrẹsi la idi a b a j ọ nkan ti on pe e si. O ni on ṣe akiyesi wipe lati igba ti o ti gun ori oye Emir ni Ilọrin ni nkan ti bẹrẹsi gun rege-rege ni ilu na ati ni awọn agbegbe rẹ. O ni nitori eyi ni on ṣe pe e lati da lọla pẹlu ida Olowoyebiye lati ma fi ge okun irọ awọn onirikiṣi ati oni tẹmbẹlẹkun ti o wa ni ilu Ilọrin pẹlu agbegbe rẹ.

Bi Ọba Ilọrin paapa ti gba ida yi tan lọwọ Sardauna, tio fi ida na s'ọtun, ti o tun fi i s'osi, ti o si la a bọrun ti gbogbo awọn ti o wa nibẹ da muso fun un, ni Ọba na wa bẹrẹsi sọrọ.

O ni on dupẹ lọwọ Ọlọla Ahmadu Bello fun ọla ti o da on yi ati fun gbogbo nkan mere-mere pẹlu ileiṣẹ ti o nda silẹ fun awọn ara ilu on. Ọba Ilọrin ni on fẹ ki Ọlọla Ahmadu Bello fọkan ara rẹ balẹ nitoripe on ko ni kuna rara ninu igbẹkẹle ti o gbọkẹle on.

Ọba Ilọrin ni ko nṣe awọn oni tẹmbẹlẹkun ati oni risiki nikan ni on yio lo ida na fun: o ni on yio lo o fun awọn ariṣẹmaṣe ti o wa ni Ilọrin pẹlu ẹlẹtan ibẹ ati awọn ti iṣẹ riba jijẹ ti gba ọkan wọn patapata. O ni on a ri wipe gbogbo awọn ti o wa labẹ on mbẹru Ọlọrun ati pe ko si wipe Olowo kan nrẹ talaka kan jẹ mọ. On a si tun ri wipe gbogbo awọn adajọ Kotu nṣe idajọ ododo.




## Ogbeni Ayuba Kottun Komojade

Laipẹ yi ni Suru-Lere ni Ọgbẹni Ayuba Kọttun, ti o nṣe iṣẹ ninu ile awọn Oyinbo onisowo ti a npe ni G. Gottschalk ("Ọlọwọ") l'Ẹhingbeti l'Eko, ṣe ikomọ ti iyawo rẹ 'Bọdunrin (ọmọ Ibarẹ-Akisan) bi fun un. Nwọn sọ ọmọ tuntun na ni Ọlawale.

Gbogbo awọn ọrẹ ati ẹbi ni nwọn pe'sẹ si ibi aṣeyẹ ikomọjade na; baba ọmọ tuntun na si fi onjijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn ti o wa sibẹ lọrun.

Diẹ ninu awọn ti o wa si ibi ikomọ na ni awọn Ọgbẹni Bọde Vaughan, Ayinde Mati, Dele Johnston, Ọgbẹni Layọ Kufeji ati aya rẹ, Iyabọ, Iyafin Irene Munis, Shonibarẹ, Tayọ Macaulay, Simbiatu Agunbiade, ati Amudatu Agunbiade.

**Wo oju ewe 5 ati 6 fun oro Ayiluka ati Enkuari.**

## Nigerian Ports Authority

INVITATION TO TENDER SCRAPS

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of Scrap materials now lying at the Authority's premises at Port Harcourt.

2. A copy of the tender form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, or Port Manager Eastern Ports, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt, on payment of a deposit of £5 (Five pounds) to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays, or to the Area Accountant, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt. The completed tender form should thereafter be addressed to the Secretary to the Authority in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP MATERIALS" so as to reach him not later than 11th August, 1962.

3. The successful tenderer will be required to remove the Scrap at his own expense within 7 days of the acceptance of his offer. The deposit of £5 (Five pounds) will not be refunded in any event to any tenderer who, upon being advised of the acceptance of his tender fails to pay for and remove the Scrap. He will also be required to make necessary arrangements at his expense for the Scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

4. Tenderers are warned that Scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials, although it is expected that most of the material will be ferrous.

5. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

BAYO KEHINDE,
Secretary to the Authority.

N. P. A. Notice No. 732.
23rd July, 1962.

# ELETI-OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 468 Phone 23370.

VOL XIV. No. 831. SATURDAY AUGUST 4,-AUGUST 10, 1962.

## Aiye Ko Otitọ

AWỌN baba wa ni nwọn ma npa owe kan wipe "Orin ni ṣaju ọtẹ". Owe yi bi o ti kere to ti ọpọlọpọ awọn enia wa ko nka a si, o jẹ asaro ọrọ ti o nṣe bẹbẹ ni ode ti a wa nisisiyi.

Bi iwọ ti o ba nka iwe wa ọsẹ yi ba jẹ onigbagbọ ti o fi Jesu Krisiti ṣe apẹrẹ igbagbọ rẹ wa ri wipe nigbati Jesu Krisiti na wa laiye ti o bẹrẹsi ba awọn enia rẹ sọrọ bi nwọn ṣe le ma gbe ni irẹpọ, ti nwọn si le gbadun aiye wọn. Awọn enia na kọ tirẹ, nwọn ko si gba gbogbo nkan ti o nwi nitoripe AIYE kọ OTITỌ.

Nigbati nwọn bi Anabi Mohamed (ikẹ ati ọla fun un) si ilu Mẹka ti o dagba tan, ti o bẹrẹsi ṣe waasi fun awọn ọmọlẹbi rẹ, gbogbo wọn bẹrẹsi yọ ṣutuete si i. Kilo fa a ? Nitoripe ara awọn araiye ko otitọ ni.

Ki a tun wa pada sile lọdọ awa Yoruba, nigbati ỌRUNMILA AGBỌNNIREGUN bẹrẹsi ṣe ikede tirẹ kakiri larin awon ara wa, awada ni nwọn nfi ọrọ rẹ ṣe nitoripe Woli kan ko nni iyi ni ilu rẹ.

Bi o ba jẹ Alufa ṣọsi ti o ba nsọ otitọ pupọ ju awọn Ijọ a salọ mọ ẹ loju. Bi o ba ti jẹ Lẹmọmu ti ọrọ waasi rẹ ba le, awọn JANMA a tuka, o ko si ni ri JAKA pupọ gba bi AWẸ ba pari

Ọrọ awa Eleti Ọfẹ ti ọsẹ yi jọ bi owe bi owe, bẹni a ko ba ẹnikan wi rara, iwasu atata ni a nṣe fun awọn ọkawe wa.

Ẹniti o ba ni eti ki o gbọ Aiye kọ OTITỌ.

## OKUJA WỌ'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA. BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE

TI ỌJA LE FI MA TA
BI IṢU AKARA GBIGBONA.
POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—ỌFẸ

# Iwe Si Olotu

## Apania Niwon Nitoto

Ẹ nu ya mi pupọ lati ka irohin kan ti o jade ninu iwe yin Eleti-Ọfẹ ti ẹnu lọlọ yi ti nwọn sọ wipe ni agbegbe ilu Kalaba (Calabar) awọn oniṣegun kan fẹran lati ma ba awọn obinrin aboyun ti o nrọbi lọwọ sun ti nwọn ba ti gbe wọn de ọdọ awọn oniṣegun yi.

Olotu, mo faramọ ọrọ ti Oloye B.C. Okwu tiṣe Minisita Alabojuto eto iṣẹ ilera Ipinlẹ na sọ wipe on gba ni imọran fun Ijọba Ipinlẹ na wipe ki nwọn ṣe ofin lati mọ ba awọn ti o ba nhu iru iwa bẹ ro ẹjọ apania nitoripe oju iku ni awọn aboyun nwọnyi wa nigbati nrọbi.

Mo fẹ ki ẹ mọ wipe ni ilu Ibo nikan kọ ni iru iwa yi pọ si, diẹ ninu awọn oniṣegon wa miran ti nwọn ko bẹru Ọlọrun nṣee, ṣugbọn ọjọ idajọ wọn ku si dẹdẹ.

Emi ni,
Ilaro A. Idowu

## Ibaje Awon Omo Araiye Po

Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye ninu iwe irohin nyin lọsọsẹ lati le ma fi iwasu diẹ diẹ si awọn ọmọ araiye leti ninu Eleti-Ọfẹ nitoripe iwa ibajẹ awọn ọmọ araiye na pọ lapọju o si yẹ ki a mọ si wọn leti boya nwọn le yipada kuro ninu aiṣedede wọn.

Mo nreti esi yin.

Emi ni,
Evanglist M.A. Adetula

Agege Motor Rd.,
Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba kọ iwe ti o mu'fọgbọn dani si wa ao tẹ ẹ, ko ba jẹ irohin tabi itan nipa ilu tabi nkan abalaiye ni.

Olotu.

## Ikomo Omo Ajala Dun

Ọlọrunṣogo, Mushin—Ni ọjọ Abamẹta tiṣe ọjọ kejidinlogun oṣu ti o kọja ni Ọgbẹni Ọlajide Ajala ti o nṣe iṣẹ ni ile awọn Oyinbo John Holt l'Eko ṣe ikomọ ọmọkunrin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ Grace Abẹni lọrẹ. Nwọn si sọ ọmọ na ni Gbọlahan. Gbogbo ẹsẹ awọn enia pataki pataki ni o pe sibẹ paapa awọn ọmọ ẹgbẹ Ifẹlodun lati Ebute Metta. Awọn elere onilu kan ti nwọn npe ni Jeremaih Orchestra ti Garden Eden fi ilu ati fere wọn da gbogbo awọn ti o wa si ibi ikomọ na lara ya. Baba ọmọ tuntun na si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn ti o wa si ibi aṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni J. Ọladoyinbo Ajala, S. A. Suberu, J. Adetunji Ajala, Wahabi Adeṣina, S. B. Emanuel, D. O. Ọlafinhan, S. A. Adebakin, Ajani Ajala, Ọla. Ọnatade, S. A. Kilanko, A. Abọsẹde, E. O. Fọlarin, A Oyekanmi, Akanni Ajala, T. Olikama S. Ajibọla, J. O. Bello, Y. Akintọla, M. A. Ṣonẹyẹ, A. Abiọla, E. A. Ayọdele, M. A. Adeyanju Iyafin Ọlayinka Apesin, Awanatu Abikẹ, Stella Ajala, Ibironkẹ Ajala, Yinka Lufowora, F. O. Ajala, K. I. Shobande, Taiwo Ajala, Bade Ajuwọn, F. O. Olutimirin ati J. O. Ajala.

A ki gbogbo awọn ti nwọn nawo ni ibi ikomọ na, ire a kari o.

**Ko Iwe si Olotu Eleti-Ofe Fun Ibere Oro Tabi Irohin Ilu yin.**

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Ijo Nru

Ṣe ẹko binu pupọ aye ti mo fi gba awọn oni ọrọ ẸNKUARI (tabi ẹ ti npe wọn — —awọn oniwadi?) lati sọ irohin nkan ti nwọn wi ninu ile igbẹjọ wọn l'Eko ninu ọsẹ ti o kọja. Ṣe ọna ko gba ni aye ko gba. Ṣugbọn lọsẹ yi ma ba yin sọ diẹ ninu awọn ti nwọn lọwọ lẹsẹ ninu ọrọ ẸNKUARI na lọmọde lagba. Eyiti mo ba sọ ti o ku diẹ ki o to ki ẹ jọwọ ki ẹ dari-jin mi nitoripe bi a ba jẹkọ a ni lati darijin ewe ti a fi pọn ọn.

## Alufa Sanra

Mo gbadun awọn ọmọ ẹgbẹ onirugbọn ti a npe orukọ ẹgbẹ wọn ni Nigerian Youth Congress (NYC). Mo lọ si ibi ipade kan ti nwọn ṣe laipẹ yi nipa awọn ẹgbẹ oṣelu ti nwọn fẹ ṣe babansiku nitori ati pin ogun Ẹgbẹ Ọlọpẹ. Emi alara paapa nmura lati Lu ọpọlọpọ irun-agbọn ki mba le jẹ ọkan ninu wọn.

Awọn ọmọ ẹgbẹ onirugbọn yi ni ko si ọna rikiṣi ti awọn ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ati ẹgbẹ Ọlọmọtuntun fẹ gba ṣe "ọmọ-meji da'wo silẹ" nipa ọrọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti ko ye awọn; nwọn ni gbogbo rẹ ni awọn ti ri pe ọrọ "rikiṣi pa wọn pọ, nwọn d'ọrẹ" ni.

## Egbe Onirungbon

Mo ti ngba lero lati f'orukọ silẹ lọdọ awọn ọmọ ẹgbẹ onirungbọn tipẹ, sugbọn gbogbo igba ti mo ba lọ si ile Alagba wa Ọgbẹni Ọtẹgbẹyẹ (Alagba ni a pe ẹniti o ba hun irun agbọn) ni ọna Yaba emi ko mba a nile; bẹni eto ẹgbẹ wọn dara pupọ a fi ẹniti ko ba ye yeke-yeke.

Mo wa ri wipe ọna ti la fun mi nisisiyi nitoripe Alagba wa Oba C. D. Akran paapa ti da irungbọn si jaburata. Nigbati mo pade rẹ lọsẹ ti o kọja nibi ọrọ iwadi, nko tete mọ wipe Alagba ọrẹ mi ni nitoripe o jọ Ọba Abisinia pẹlu irugbọn ti o hu na.

Mo bi lere wipe kinni o de, o ni nipa ọrọ gbọnmi si, omi ko to to bẹ silẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni, o ni bi on ko ba ri iṣẹgun on ko ni fa a.

Nitotọ gbogbo wa ni a o ṣẹgun ati Egun-komọkan ti o mba wa ṣe ilu pẹlu awọn Yoruba ti o nsọ wipe ỌNA ỌFUN ni ỌNA ỌRUN.

## Ihamo Yi Po

Nwọn ni bi iku ba npa ojugba ẹni ominu a ma da k'oni—iyen ni ọrọ awọn ọrẹ mi oniwe irohin meji ti Dokita Adekoye Majẹkodunmi ni ki nwọn wa wọn lọ si ilu awọn DO, obo-ado-ri, ADORI-NA-GAGA. Awọn ọrẹ mi mejeji na ni Ọgbẹni Victor Bisi Ọnabanjọ ("Aiyekotọ") ati Abudul Lateef Jakande ("John West"); nwọn fun wọn ni iwe ihamọ apapandodo. Ọnabanjọ lọ si Forcados, Jakande lọ si Kwale ni ilu awọn Abọ. Nwọn nsọ emi Ayiluka paapa lẹnu nitorina nko ni sọ ju wipe IHAMỌ YI PỌ JU LỌ.

## Ogun Ero

Kosi nkan ti o nle ti ki rọ. Bi inu ba mbi awọn baba wa laiye atijọ nwọn a lọ mu ọti OGURỌ nitoripe OGUN—ẹrọ ni. Laipẹ yi ni mo mu awọn alejo kan ti o de fun mi lọ si ọdọ Ọgbẹni Akanbi Eko (ọmọ Agoro) ni Oke Aleji l'Eko (kiṣe oke Aleji ti Abẹokuta o) a-muyira ni ogurọ Akanbi Eko na, ogun-ẹrọ si ni. Bi iyawo rẹ ba mba ẹ ja bi o ba ti mu ogurọ yi (awọn ọmọ Eko npe ni Kasabubu) inu rẹ a rọ wẹsi, wa si rẹrin atinu wa. Mo gbọ wipe lati oko awọn Ẹgba leti Abẹokuta ni Akanbi Eko ti nda awọn oje ogurọ yi. Jọwọ Akanbi, bi a ba ti pari ọrọ ẹnkuari tan mu mu awọn oṣelu Ibadan wa ṣe faaji lọdọ rẹ. Ki o ba mi ki Kudirat ati iya rẹ pẹlu Adiatu. Ayiluka fẹ ṣe ọjọ ibi, ki ẹ fi ogun-ẹrọ silẹ fun un.

Ọrọ Ọgbẹni Akanbi Eko yi lo tun jẹ ki nrrian baba wa Ologbe Sunmọnu Majẹnrahun ni igboro Eko nigbati gari wọn bi oju. Bi Ologbe Animọ'u Pelewura ti nṣe wahala ki ara Eko ri gari jẹ bẹni Ọgbẹni Majẹnrahun (baba"Ọfẹ) paapa nṣe tirẹ.

Ọti biya (beer) ti wọn nisisiyi ogun-ẹrọ (ogurọ) loku ti awọn ara Eko nfi ṣe oge.

# Okeke Ngba Ategun Nilu Oyinbo



AWORAN yi ni ti ọmọ Ibo kan ti o njẹ Benson Okeke ti awọn Oyinbo elepo moto, Shell International ran lọ kọ iṣẹ ẹlẹrọ ni ilu Oyinpo, nibiti o gbe ngun kẹkẹ ologere pada lọ si ile ti o ngbe ni Leicestershire lẹhin ti o ti siwọ ni ile-iwe rẹ. Ilu Onitsha ni Nigeria ni ọdọmọde Okeke ti wa.

ENKUARI TUNA ASHIRI

# Ijoba Apapo Nigeria Yawo Lowo Ijoba Iwo orun Nigbakan

EKO—Enu ya ogunlogo awọn enia ti o wa gbọ ẹjọ ti awọn nro ninu ile igbimọ-nla ti Nigeria nibiti wọn nṣe iwadi awọn Ajọda-iṣẹ mẹfa ti Ijọba Ipinlẹ Iwo Orun l'Eko nigbati ẹnikan pataki ninu awọn ẹlẹri Ijọba tuna aṣiri wipe owo ti Ijọba Apapọse (Federal Government) l'Eko ya lọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun jẹ £7,000,000 nigba kan.

# Awon Tisa Ilu Ibo Fi'se Sile Nitori Owo Osu

ENUGU—O le ni ẹgbẹdogun (3,000) awọn olukọ ile-iwe ti o binu da iṣẹ sile ni ilu Ibo ni Ipinlẹ Ila orun ni aipẹ yi nitoripe awọn onişẹ wọn ko fun wọn ni owo oşu lati ọkan bi oşu keje.

Onirohin wa ṣe alaye wipe awọn agbegbe bi Buguma leti Port Harcourt, Isiokpo ati gbẹriko ti nwọn npe ni Isiokpo ni rukerudo na gbe ti bẹrẹ nitoripe awọn ọlọpanu ti tesẹ bọ ṣokoto wọn lati ṣe iwadi awọn ti o gbe ẹgbẹtala-o-dinogorun pọnun (£2,500) ti awọn Ijọ C.M.S. sọ wipe awọn fẹ fi san owo oşu fun awọn tisa na.

Pẹlu omije loju ni ọkan ninu awọn tisa na ti orukọ rẹ njẹ Agnes fi nso ẹjọ fun onirohin Eleti Ọfẹ. O ni [illegible] bi oşu karun ti on ti ngba awọn [illegible] kakiri nig. O [illegible] nigbati ọrọ on su gbogbo awọn ara adugbo, nwọn ko ile fẹ ṣe on lanu mọ nitorina on ni lati wa iṣẹ tisa on si ibomiran.

### Tisa Ife F'ake Kori

Irohin kan pataki ti o tun kan wa lọwọ ni ti awọn olukọ ile-iwe giga kan ti nwọn npe ni Oduduwa College ni Ile Ifẹ ti gbogbo wọn ti akee kọri wipe ti nwọn ko ba san owo oşu awọn ni asanpe awọn ko ni ṣe iṣẹ rara.

Nwọn ni ninu oşu (July) ti o kọja yi ni awọn to gba owo ti oşu kẹta (June) ọnuẹ. Ọgbẹni A. Obisẹsan iṣẹ akọwe awọn olukọni tisa ni ọrọ na ko ye awọn rara nitoripe awọn ko tilẹ ri ọga-agba ile-iwe na lati ba a sọrọ ki awọn le mọ nkan ti o fa sababi ọrọ na.

### Banki Agbonmagbe

Nigbati awọn oluwadi tun bẹrẹsi ṣe iwadi wọn ni ojọ Aje ti o kọja yi, Oloye Samuel Durosarọ, Alaga ile ifowo pamọ ti National Bank ti Nigeria ni ẹleri ti o si wa ninu apoti-ẹlẹri ti awọn lọya lotun losi ngbo jigijigi pẹlu ibere ọrọ ti nwọn fi nwa idi ọrọ nipa owo ti Ile Iṣẹ Rira ati Tita koko (Cocoa Marketing Board) fi ya awọn ẹgbẹ onisowo ile-kikọ ti nwọn npe ni Nigerian Investments Properties Company (NIPC) atiowo ti nwọn fi pamọ si ile ifowo pamọ ti nwọn npe ni Agbọnmagbẹ Bank ati bi diẹ ninu owo na ati bi awọn se se ni owo ajọpin-iṣẹ (shares).

Oloye Durosarọ ni gbogbo owo ti awọn fi si Bank Agbọnmagbẹ jẹ £200,000, ṣugbọn nigbati awọn ṣe akiyesi pe "ẹmi Bank na ko de" ni Oloye Akintọla, nigbati o bọ si ori aga Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, ni ki awọn fi ọkẹ mẹrin pọnun (£80,000) ra ajọpin-iṣẹ (shares) ninu iṣẹ Bank na.

## E ka Iwe Irohin ELETI OFE


CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT:
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

WORLD HEALTH MEN

# Rush Medical Aid To Cotonou

TO PREVENT EPIDEMICS

DAHOMEY—Immediate assistance is being furnished by the World Health Organization, at the request of the Government of Dahomey, in preventing the possible outbreak of epidemics threatened by the disastrous inundations from which the city of Cotonou continues to suffer, as a result of persistent torrential rains.

A WHO sanitary engineer, already on the spot, and a WHO Medical Officer who arrived over the week-end, are conferring with the Government to ascertain the stricken city's requirements in medical personnel and medicaments. Another WHO Medical Officer is on the way from Ouagadogou, Upper Volta. A third Medical Officer has been diverted to Cotonou, on his way from WHO Headquarters in Geneva to the Regional Office for Africa, at Brazzaville.

Furthermore, additional WHO medical personnel, including doctors, nurses and sanitary engineers, stationed at field projects in various parts of Africa, have been alerted to stand by for departure to Cotonou, if their presence is needed.

# Farming Tractors For Kenya Farms

NAIROBI—The importance of machinery to the new African farmers on their small-holdings, was stressed by Mr. Michael Blundell, Kenya Minister of Agriculture at the Royal Show in Nairobi, when he handed over two Massey-Ferguson tractors to the principals of two leading Agricultural training colleges.

"No farmers," he declared, "could be successful without understanding machinery, and the problem facing the Africans was how to obtain maximum output without having to carry on old-fashioned methods."

The tractors, an MF35 and an MF65, together with two disc ploughs, an offset forager and an offset disc harrow, were a gift from Massey-Ferguson to Egerton College, in the Kenya Highlands, and Siriba College, not far from the shores of Lake Victoria.

# Founder Of German Radio Dies

BERLIN—Dr. Kurt Magnus, whose name is intimately connected with the history of German radio, died recently at the age of 75 years. Dr. Magnus played a leading role in the organisation and development of the broadcasting system in Germany.

He was one of those people who establised the Berliner Funstunde in 1923.

Two years later, he and State Secretary Bredow founded the Reichsrundfunk-Gesellschaft, in which were associated the nine independent broadcastidg corporations that existed in Germany at that time. At first Dr. Magnus was the association's business manager, later the chairman of its board. He actively participated in the planning of the radio programmes of that day.

In 1933, Dr. Magnus was ousted from his position by the Nazis. Immediately after World War II, however, he placed himself at the disposal of re-organisers of German radio.

The legal form of the German broadcasting system is largely his work. Towards the end of his life he was chairman of the administrative board of the radio station in Hesse. He held this position until his death.

## British Research Doctor For Lagos' New Medical School

BIRMINGHAM—Dr. G. H G. Davis, a member of tee British Medical Research Council staff and Fellow of Birmingham University has been appointed senior lecturer in the micro-biology department of the new medical school which opens in Lagos in September.

# Dont Waste Water



## Ewu Lo Lori Dokita Nkrumah

ACCRA—Ewu lọ lori Dokita Kwame Nkrumah, Alakoso Ijọba ilu Aganyin (Ghana) ni alẹ ijẹrin iṣe ọjọ kini oṣu yi nigbati afọnja ẹtu (bomb) kan fi t'agbara t'agbara tuka bi Alakoso yi ti fẹ bọ silẹ ninu mọto ayọkẹlẹ ni abule kan ti nwọn npe ni Kungungu ni ilu oke awọn Aganyin na.

Irohin ti awa Eleti-Ọfẹ gbọ nipa ọrọ na ni wipe lojọ ti ijamba yi ṣẹlẹ, Dokita Nkumah pẹlu diẹ ninu awọn ọmọlẹhin rẹ mura, nwọn nlọ ṣe abẹwo awọn ilu ti o wa labẹ Ijọba wọn ni ilu Oke Upper Volta ni Tamale. Nigbati nwọn de ileto ti nwọn npe ni Kungungu yi nwọn ri awọn ọmọ ile-iwe pẹlu awọn tiṣa wọn ti nwọn to si oju ọna lati damuso fun wọn.

Dokita Nkrumah si paṣẹ fun awamọto rẹ pe ki o duro ki on le ki awọn ọmọ ile-iwe na daradara; bi o ti fẹ sọkalẹ ninu mọto na ni afọnja-ẹtu (bomb) na ba tuka pẹlu agbara, o si pa enia mẹrin, awọn ọlọpa meji pẹlu ọmọde kan bamu-bamu. Awon enia mẹrindinlọgọta ti ẹtu afọnja na ṣe ni jamba, ti nwọn npoka iku ni nwọn ti fi mọto ru lọ si ile alaisan ni Tamale.

Nkankan ko ṣe Dokita Nkrumah paapa alara sugbọn awọn ọlọpa wa a ninu mọto ayọkẹlẹ lọ si ilu kan ti nwọn npe ni Bawku lati lọ yẹ ẹ wo ni ile alaisan fun rabọ-rabọ ẹtu na ti o ta ba diẹ.

Awọn ọlọpa si wa lẹnu nwọn nwa awọn ti o ṣe iṣẹ buburu yi kiri.

## Baba Onimoto Tun So Ọmo Kan Di Ọdi

Baba onimato kan tun sọ ọmọdekunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Olu Awonusi, ọmọ ọdun mẹrindinlogun, di odi ni Popo Aguda ni ijẹta. Ọmọ na si fi iwe sọrọ fun awọn Ọlọpa bi o ti ṣe di odi. O ni awọn ọkunrin onimọto kan ni nwọn ni ki on bọ si inu mọto ki on fi Lewis Street han awọn.

Olu ni nigbati on bọ sinu mọto wọn na, ọna Ikorodu ni nwọn gbe on gba ninu igbo kan, o ni bi awọn ti nlọ ni nwọn ti fi ogun kan gba on loju ti eti on si di bamu bamu ti on ko si le sọrọ mọ. O ni nwọn gba asọ on ati pọnun meje ti nwọn fi ran on nṣẹ; o ni iro ibọn ọdẹ kan ti nwọn gbọ ninu igbo na ni o gba on la ti awọn ọkunrin mẹtẹta na ba fi ju on silẹ ti nwọn ba fi salọ.

x L'owurọ ana, ọkunrin kan ti a ko mọ orukọ rẹ ku si isọ awọn alasọ lilọn l'Ereko ni Eko. Awn ọlọpa ti ru oku Ọgbẹni na lọ.

## ỌRỌ ẸNKUARI:

## Awosika Paapa

### YAWO LỌWỌ I GBIMỌ ATA-KOKO

EKO— Awọn igbimọ Oludari iwadi (Ẹnkuari) ti Ijọba Apapọṣe paṣẹ wipe ki nwọn ṣe iwadi pataki lori ọrọ ajọda iṣẹ mẹfa ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun mba iṣẹ wọn lọ. Ni ọsẹ yi, ẹlẹri pataki ti o tun jẹri nibi iwadi na lẹhin Oloye S. L. Durosarọ, alaga ile ifowopamọ National Bank Nigeria, ni Ọgbẹni Adewuyi Ladẹinde, akọwe onișiro-owo Igbimọ Ile Iṣẹ Rira ati Tita Koko (Cocoa Marketing Board).

Ọgbẹni Ladẹinde niile iṣẹ Rira ati Tita Koko yi fi £850,000 pamọ si National Bank nigba kan, ninu owo yi ni nwọn ti mu £500,000 ti nwọn fi ya awọn ẹgbẹ onișowo ti nkọ ile (NIPC). O ni ti o ba jẹ wipe awọn ọga on bere imọran lọwọ on ni Ladẹinde ni on ko ba ti jẹ ki nwọn ya awọn ẹgbẹ onișowo yi ni owo na rara.

Lẹhin igbati Ọgbẹni Ladẹinde ti sọ gbogbo ọrọ tan ti Oloye Awolọwọ bẹrẹsi bii lere ni ẹlẹri yi ni nitotọ on ṣe akiyesi pe owo ti o wa ni apo igbimọ ata-koko pa ni iwọn ọdun meji sẹhin gbe bukẹ, sugbọn lẹhin eyi ni owo ko ti wọle pupọ fun awọn mọ.

Ninu idahun rẹ miran, Ladeinde ni Alaga Igbimọ ibi iṣẹ ata-koko, Oloye F. O. Awosika paapa ya ẹgbaa pọnun lọwọ Igbimọ na bẹna si ni Oloye S. L. Durosarọ ti o ti nṣe laga Igbimọ ri gba ẹgbẹrun pọnun lọwọ Igbimọ na, nkan ti nwọn fi owo na ṣe ko ye on rara.

Advt. No 134

## NOTICE

### NIGERIAN HONOURS, DECORATIONS AND AWARDS

The National Committee on the award of Nigerian Honours would welcome suggestions from the general public on the following questions:-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should ALSO be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting foreign dignitaries ?

(ii) Do you consider that such awards should take form of:-

(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or

(b) decorations, which qualify recipients to wear medals on ceremonial occasions, or

(c) both, or

(d) neither ?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government ?

2. Please address all communications to :-

The Secretary,
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are forwarded to Secretary not later than the 30th of September, 1962.

## Omo Awolowo Loya Ti Ilu Oyinbo De

EKO—Ayọabara tintin, ọmọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti o njẹ Olușẹgun, ti o ṣẹṣẹ pari iṣẹ lọya ti o ti nkọ ni ilu Oyinbo ba ọkọ oju omi de si Eko ni ijẹta ọjọ Alamisi ti awọn Yoruba npe ni Ọjọbọ. Gbara ti o ti yọ'ju ninu ọkọ ni Apapa iya rẹ (Oloye H. I. Awolọwọ) ni o kọ ri pẹlu awọn ti o baa wa si ebute lati pade rẹ.

Oloye Awolọwọ, baba ọmọ na ko le wa nitori ihamọ ti o wa pẹlu iṣẹ nla ti o nṣe nibi Ẹnkuari (iwadi) l'Ọdan ni Eko, șugbọn Olușẹgun, lọya tuntun yi gun mọto ayọkẹlẹ lọ ba a ninu ile Igbimọ ti nwọn ṣe iwadi na, gbogbo wọn si jọ kẹsẹ wa si ile ti Oloye Awolọwọ ngbe ni Ikoyi

Ni ọtunla (Monday) ọjọ Aje ni ọmọ na nlo bura ni iwaju Adajọ-agba ni Kotu ganran ti yio si bẹrẹsi ṣe iṣẹ lọya (lawyer) rẹ. A ki awọn ẹbi Awolọwọ, nwọn ku afojuba.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23570; EDITOR (OLOTU): OLA ONATADE, 15, Kosoko St., Lagos,